# IROHIN IMOLẸ

IMOLẸ ỌRẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 706 FRIDAY, MAY 29, 1964 (2D)


## ẸGba a Awọn Agbẹjọro Lo Wa Pẹlu Okpara

POTA:— Dokita Michael Okpara Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ila Orun Naijiria ati Olori ẹgbẹ Alakukọ sọ fun ipade awọn Ọmọ ẹgbẹ rẹ ni Pọta ni Ọjọ Aiku ti iṣe Ọjọ kẹrinlelogun Oṣu yi pe, Igba (200) awọn Agbẹjọro ni nwọn wa lẹhin on lati ba Apapọ Ijọba Naijiria ṣẹjọ ti Ijọba on pẹṣẹ laipẹyi.

Dokita Michael Okpara na tun ṣe alaye pe, awọn Amofin na kọwe si on pe, ohun ti Ijọba on pe Apapọ Ijọba lẹjọ le lori gbogbo awọn ni ọran na yio kan ni Ọjọ iwaju.

O ni awọn enia na wa sọ ninu iwe ti nwọn kọ si on pe, gbogbo awọn ni awọn yio jade ni Ọjọ ti ile ẹjọ gigajulọ fun Orilẹ-ede yi ba fẹ ṣe ẹjọ na, Ọfẹ ni awọn yio ṣe ẹjọ na, awọn ko ni gba Owo nitoripe, bi awọn ko ba kogiri si Ọran na ohunti yio kan awọn ti yio si tun kan Ọmọ awọn lẹhin Ọla ni.

Oniwe irohin wa kan ran wa leti pe, Ijọba Ipinlẹ Ila Orun Naijiria ti pe Apapọ Ijọba lẹjọ pe, Alhaji Abubakar Tafawa Balewa ko gbọdọ ṣe eto kankan lori abayọri eto ikania atipe ko si tun ni aṣẹ lati gba abayọri eto na gẹgẹbi o ti ṣe.

A ko ti mọ Ọjọ ti nwọn o ṣe ẹjọ na, ṣugbọn ti a ba ti gbọ, ao sọ fun nyin ninu iwe wa.

# AWỌN OṢIṢẸ FẸ DA IṢẸ SILẸ

EKO:- Gbogbo ile lo kunsoso ti ẹsẹ ko si gbeji fun ogunlọgọ ọkẹaimoye awọn enia ti nwọn wa sinu ipade ti gbogbo awọn oṣiṣẹ ṣe ni ọjọ ọjọ 'Ru ti ise ọjọ kẹtadinlọgbọn osu-yi nibiti gbogbo wọn ti pinnu ti nwọn si fi ohun sọkan pe gbogbo awọn oṣiṣẹ Ijọba jake jado erilẹ ede yi ni yio da iṣe silẹ ni ọjọ Aje ti ise ọjọ kini osu ti mbọ yi.

Awọn Asiwaju Igbimọ ẹgbẹ awọn oṣiṣẹ na se alaye pe, awọn ko ni itẹlọrun si iwadi ekunwo osu ti Igbimọ Morgan ṣe ti o jade yi.

Awọn enia na ni, eyi tilẹ tun dara ju iwe ero Apapọ Ijọba lori iwadi ẹkunwo owo osu na ti ko ti jade lọ

Nitori idi eyi awọn Asiwaju Igbimọ ẹgbẹ oṣiṣẹ na sọ pe ti Apapọ Ijọba ko ba fi le gbe iwe ero wọn lori iwadi ẹkunwo owo osu na jade ninu ọsẹ ti a mba lọ yi gbogbo awọn oṣiṣẹ Ijọba ati ti awọn Oyinbo onisowo ni yio da isẹ silẹ ni ọjọ kini ọsẹ ti mbọ yi ti ise ọjọ kini oṣu kefa ọdun yi.

Awọn enia na ni awọn ti mu suru to fun Apapọ Ijọba ṣugbọn o dabi ẹnipe Ijọba fẹ maa lo awọn ni ilo omi ojo gẹgẹbi o ti ṣe wu wọn.

Alhaji Adebọla sọpe, ki ṣe nitori abayọri eto Igbimọ iwadi ẹkunwo oṣu awọn oṣiṣẹ ti o jade ni awọn oṣiṣẹ yio ṣe kọ iṣẹ silẹ, ṣugbọn nitori ipinnu Apapọ lori iwadi ẹkun owo oṣu na ti Ijọba ko ti gbe jade titi ti o fi di isisiyi.

Alhaji na tun sọ siwaju ninu ọrọ pe, gẹgẹbi ou ti nfi oju inu wo ọran na, ko ti si oluwadi ẹkunwo owo-oṣu ti o da imọran ẹkunwo fun Apapọ Ijọba, iru eyiti Igbimọ Ọlọla Morgan dayi.



Alhaji H. P. Adebọla

Ṣugbọn ohunti o ya enia lẹnu iru eyiti ko ṣẹlẹ ri, ni wipe, ti iwadi Igbimọ ba ti jade, bẹni Ipinnu Ijọba yio ti jade lori iwadi na, ti yio si sọ ewo ninu imọran na ti Ijọba y o faramọ, ewo ni nwọn o si yọ sẹhin ninu rẹ.

Alhaji Adebọla ni, Igbimọ Morganti sọ ohuntiwọn ri ati ohunti nwọn fẹ ki Apapọ Ijọba o ṣe ṣugbọn Ijọba le gba imọran na nwọn si tun le kọ ọ.

Nitori idi eyi, Alhaji Adebọla ni awọn ko ti mọ ero Apapọ Ijọba lori abayọri Igbimọ awọn oluwadi ẹkunwo oṣu fun awọn oṣiṣẹ

O wa rọ gbogbo enia pe, "a ki ifi oju borọ gba ọmọ loju ekurọ bi Apapọ Ijọba kọ ba fẹ sọ ero wọn jade pẹlu ẹrọ nwọn o sọ jade pẹlu "ipa kia-kia"

Alhaji na tun sọ siwaju ninu ọrọ rẹ pe, "Awa paapa ko ti le gba abayọri eto iwadi owo oṣu Morga, bẹni a ko si ti le kọ ẹkunwo oṣu na bayi, nitoripe a ko mọ ero Ijọba."

O tun sọ pe "Awọn oṣiṣẹ ti mu suuru to fun Apapọ Ijọba lori ọrọ yi, ti o fi jẹ wipe agara ti da awọn lori ọran na, Ijọba si gbọdọ ni itelọrun ati ifarada

WO OJU EWE KẸFA

# AwẹFẹ Kuro LabẹỌyọ

AWẸ:- Ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹdọgbọn oṣu yi irohin kan wa ninu ile iṣẹ wa pe, awọn ọmọ Awẹ fẹ daduro gedegbẹlai durolabẹ ilu kankan, ki nwọn si ni Ijọba Ibilẹ ti yio ma aṣẹ atun ilu Awẹ ati agbegbe rẹ.



Ologbe Oloye J. A. Ajao
*Balogun Awẹ Ọtun-Ọyọ*

Oniwe irohin wa kan fi ye wa pe, Ijọba Ibilẹ ti Awẹ fẹ gba yi ni yio ma a ṣe eto ilu Awẹ, Akinmọrin Fiditi, Ilọra, Iware, Jobele ati awọn ilu kekeke miran ti o ba wa pẹlu wọn.

Nigbati Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ba gba fun wọn lati da Ijọba Ibilẹ na silẹ Orukọ ti nwọn o ma a pe Ijọba Ibilẹ na ni AFIJIO

Oniwe irohin wa Ejonboro, fi ye wa pe, nigbati on gbọ Irohin na ni on ba lọ Ile iṣẹ Minista Alamojuto eto Ijọba Ibilẹ lati lọ wa di ọrọ na. Agbọrọsọ ile iṣẹ Minista na fi ye Ejonggboro pe, nitotọ ni awọn ti ri iwe gba lati Awẹ pe, nwọn fẹ kuro labẹ Ọyọ, ṣugbọn Ijọba Ipinlẹ ti fọwọ si iwe na pe, ki Awẹ ma a ṣeIjọba Ibilẹ tirẹ lọ tọ

Agbọrọsọ natun fi ye wa pe Ijọba Ipinlẹ yio tẹ iwe aṣẹ ti nwọn ti fọwọ si na sita fun gbogbo aiye gbọ lai pẹ; lẹhinna ni Ijọba yio wa dagbere fun Awẹ pe, E ma a lọ ṣe Ijọba ara nyin, ẹ kuro labẹ Ọyọ.

# ITAN AJIRAN ILU AWỌN OKU ( Apa 11 )

## Lati Ọwọ J. O. Shoyinka

Nihin ni awọn ẹbi Ogbojuleogun ti ba a sọrọ pe ki o sa agbara rẹ gẹgẹbi a k ọ n i enia. Ẹ ma a ka itan na lọ.

Ki oto wi bayi tan Ogbo juleogun ti kan an lara, ija bẹrẹ, bi ere bi awada, bi ere, bi awada, Ogboju-leogun la Agidi mọlẹ. Ohun ti ko jọ obinrin lọju, ni o nkun wa ninu ni ero yi jẹ fun Agidi.

O ti Agidi bọ ọ, erukuru nta, ariwo nta gee awọn ẹgbọn Ogbojuleogun ti gba pe nihin ni ẹmi aburo wọn yiọ pin si. Ti Ogbojuleogun ba lọ Agidi ni tiorin Agidi ayi si alogbe, ti Agidi ba ṣa Ogbojuleogun lẹpa Ogbojuleogun ayi si ẹgandi.

Nwọn ja ija yi fun wakati kan, ko si ẹniti yio la wọn. Arẹ bẹrẹ si mu Ogbo juleogun, agbara rẹ ndikun kaka ki agbara Agidi dinku npele si npele si i. Bi Agidi ti gbe Ogbojuleogun lẹsẹ ẹ tan ru, Ogbojuleogun la mọ lẹ, ko ṣen ko seji, o ke pe Ayọrunbọ fun iranlọwọ. O ni Ayọrunbọ o! Ayọrunbọ!! Eiyẹ buburu ti njẹ larin ajẹ, Agidi fẹ la on pa o

Lọgan Ayọrunbọ di kukute o d u r o sẹhin Agidi ibiti o ti nja sihin ja sọhun o ta lu kukute, o ṣubu lulẹ, o ṣi ṣọ lẹsẹ. Ọrẹ na fẹ mu itiju wa, eyi mu ki Agidi fi ẹgbọn agba fa Ogbojuleogun, mọra, o nsọ bayi pe:-

Iwọ Ogbojuleogun, ọmọ ekere ṣinṣin ni o, nko si fẹ ba ọ ja ija agidi. Ere gan an ni on mba ẹse, bibẹkọ mba kọn ni alapa ni fi eti silẹ ki o gbọ itan ti ngo sọ fun ọ yi, ohun ti o ṣẹlẹ si mi alara paapa ni, on na lọ si sọ mi dẹni aja ilẹ.

"Bi a ba wi f'ọmọ ẹ n i agbọ, bi ko si gbọ ori rẹ koko lawo ( O w e Ọkẹrẹ ) Agidi pali baba Bilisi paṣẹ fun Bilisi ọmọ rẹ pe ki o tẹ eni si ita, o tẹ ẹ o si tun sọ fun iyawo rẹ ti a npe ni Aṣeju pe ki o gbe iyan atata fun awọn ọmọ Onilogbo.

Ki o to gbe onjẹ yi ka ori ẹni tan, itọ nla kan ja bọ silẹ l'ẹnu Ige, nitoripe o ti nreti onjẹ ti pẹ. Aṣeju iyawo Agidi ko kẹrẹ nipa ọbẹ sise, idi rẹ ti awọn iya-ọkọ re ma fi npe ni ọlọwọ sibi niyẹn.

Inu pakata nla lo gbe Iyan na o de lade ẹgusi, a w ọ n ọgbẹni bi iru ati iṣapa bo iyan loju, ẹrak ori rẹ ri kun gbẹkugbẹ, o din in o bi sansan. Iṣẹ bẹrẹ olukaluku bẹrẹ si fọn iyan, bi k u m ọ kondo, bi ori abiku rigidi—rigidi ni nwọn mbu i y a n na, ọna ọfun wọn nro gbagba-gba bi igi ẹgba ti aṣẹ fun idana, lọgan iyan ti tan

Wọn mu omi le e l o r i ọkan wọn si balẹ, olukaluku yan ikun silẹ, o nja rodo bi ti aboyun awọn bẹrẹsi gba atẹgun. Lẹhin ija ọjọ kini ni Agidi ati Ogbojuleogun ti di ọrẹ timọ.

Nwọn a si ma a ba a r a wọn sọrọ ijinlẹ. Ṣugbọn gẹgẹbi ọrẹ atata Agidi ni on ko le sai gba wọn ni iyanju. O bẹrẹ itan ati ọrọ iyanju rẹ bayi pe:— "Iku Li i pani arunkii pa enia, ohun to yara pa enia bi aṣeju kosi"

O ni ni ọjọ kan Iku, Arun ati Aṣeju to Ọlọrun ọba lọ lati lọ gba agbara kun agbara wọn. Nigbati nwọn de ọdọ Ọlọrun, nwọn sọ ohun ti nwọn nfẹ Edumare dahun pe ki on to le fun wọn ni agbara on fẹ ki nwọn jẹjẹ ohun ti nwọn yio fi ta ohun lọrẹ

Kini Iku gbọ bayi si, o bẹ sihin o bẹ sọhun, o nyọ ṣẹṣẹ ṣẹ oni, ki ilẹ ọla to mọ, on yio mu enia meje wa fun Ọlọrun ṣugbọn ko fi ti Arun ṣe Iku parada o di enia, o bẹ sarin ilu, o b ẹ r ẹ s i da ijangbọn silẹ ki awọn ọmọ enia ba le lu ara wọn pa, Iku nṣe lasan ni ko ri ipa kankan ṣa o joko sile aiye pẹlu itiju nreti Arun.

Nigbati Arun de o pẹ iku o ni Ọlọrun ti nreti rẹ fun ẹjẹ ti o jẹ fun un, iku rohin fun un bi on ti dọgbọn to, ki on fi le ri enia mu wa.

Ṣugbọn asan ni gbogb rẹ ja si Arun rẹrin titi oni, ṣe owa gba pe on ni ẹgbọn rẹ, iwọ iku dẹdẹgbo. ṣugbọn ni on gba. Arun rẹrin ni aṣipa owe ni pe iku ki ṣẹgbẹ arun, oni on ju iku lọ Lọnọkọna.

Arun ni iwọ iku titi silẹ ki o gbọ. Lai jẹ pe mo kọlu enia, iwọ ko le pa a, mo ni iranṣẹ pupọ awọn ọgbẹni bi atọsi, ẹgbẹikọ inu rirun, ẹfori, giri, lobu'u' eewo tuulu, akandun, jẹrijẹri, okiniṣa, emi ma fi mba ẹda ja.

Nko si le ran wọn ni iṣẹ ki nwọn kọ, ọpọlọpọ ẹda ni nwọn ko si lagbara da dubule, nitoripe ọpọlọpọ logbon ju arọ ni lọ sugbọn emi ki ran aisan wọnyi si akọn enia.

Iya mi ẹṣẹronga hiohiol emi nran si wọn gẹgẹ bi eyin papa ti mọ pe eniti ale ba doju ija kọ, ko ni se enia kalai. Bo ṣiṣẹ titi ko ni rere nibẹ, iku ọmọde ko ni wọn ninu ile rẹ on alara paapa yio wa gbẹ bi gi ọgọnwọ' ko si ogun ti ale ṣe, ti o tun le je mọ nitoripe Atunmọ logun danu ni ajẹ.

Njẹ iwọ iku dẹdẹgbo, o ha lagbara to bi? iku yara dahun pe, on ko lagbara bi ti ẹ Arun ṣaju, iku dẹdẹgbo tele e, ile ti arun kọkọ wọ bi o ti jade nibẹ tan, ko ju iṣẹju marun lọ, gbogbo awọn to wa ni bẹ bẹrẹ si wukọ omiran nkigbe ẹfori omiran ara riro, awọn ti nmu orun kọ mọ ni iwọnba.

Bẹni arun ati ile kini bọsi ekeji ti iku si atele e, nigbati o to nkan bi wakati mẹfa, arun ati iku fẹrẹ yi ilu ka tan ni awọn ọjọgbọn, ba pobarikoto nwọn fi imọ sọkan ni nwọn a tọ Adifa ilu lọ.

pẹẹ! ti nwọn gbe ọpẹlẹ ṣanlẹ, arun ati iku yọ loju ọpọn ifa pe nwọn wọ' lu, Adifa si sọ fun awọn ara ilu pe ki olukuluku wa apandi nla, ki awọn si gbe siwaju ilẹ wọn, ki olukuluku si tun ta aṣọ funfun si oriṣẹ rẹ ati pe ewọ ni lati tun gbọ pero ilu larin ilu a fi lehin ọjọ meje. Nwọn ṣe bẹ arun gba ẹbọ yi o mu epo titi re, epo nkan loju rẹ okan rẹ balẹ, o gbebe o di iku lowọ ko eki oti enia pa, awọn mejeji wa peregede.

IYOKU DỌLA



Ọgbẹni J. O. Shoyinka



AWORAN OKE YI NI TI AJIRAN ILU AWỌN OKU

# IWE SI OLOTU

## Iddo—Oro Nfẹ Atunṣe Ijọba

Olotu ẹ gba mi ni aye diẹ ninu iwe rẹ ti o njade lojojumọ ni o fun mọ yoruba fun wa ni ona ti o ntete ye wa lati ba Ijọba Ipinlẹ wa pe ki Ijọba rere na ki o le ran wa lọwọ lati fun ilu wa ni n nkan ti o njẹ wa niya. Nitoripe gbogbo awọn ilu to wa n nlẹ Ariwa gbogbo rẹ ni Ijọba na tun ṣe daada.

Ni asiko ọjọ bayi, a ki ọ oju ọna moto yatọ si ta gbogbo rẹ ni yio ti di an, fun idi eyi, a ki ri ẹto wọ rara ni asiko ojo oripe bi mọto ba ti nja koto njẹ si gegele ni ara ọ ro awọn ero inu mọto, o si tun nba mọto jẹ lu.

E jọwọ abẹ Alhaji Ọlọla hamadu Bello Sadauna lotu Ipinlẹ Ariwa ki o tewa ṣe ibẹwo ilu wa, ki a fi oju ara rẹ ri gbogbo nkan ti a nsọ yi, ki ise iro wa ninu ọrọ na.

Awọn oyinbo ni o pa e kan pe, ki ẹ ta foju a rẹ ri nkan ni ẹdodo Bẹni ọkan ba ri.

Ilu wa nfẹ ọrọ omi ti a ma mu eyiti ko ni ko un bawa ari awọn ẹbi wa i tun nfẹ ina manamana awa na yio ma taa lara giri bi ti awọn miran to a ni Ipinlẹ Ariwa.

Abẹ Ijọba rere na ki wọn a gbagbe wa o fun awọn kan meremere to yẹ ki ilu a ni yi.

Mo dupẹ fun aye ti ẹ gba a Olotu ajinde ara yio ma o.

Emi ni
Ewewunmi
Iddo-Oro.

## A Dupẹ. Sa

Mba sọ pe bi Olotu Imọlẹ ba gba mi laye kin Ọlọla wa Dọkita Nnamdi Azikiwe ku rire ati o ṣeun nipa awọn orisiṣi im ran ati ẹkọ ti o nkọ awọn nia Naijiria nipa eto wa ninu Ijọba Apapọ.

Mo ki Dọkita wa na pupọ nipa ọrọ ti o ba awọn enia sọ inu ile ẹkọ giga julo ti Nsukka i ojo kẹdogun oṣu karun ọdun i eyiti o pe akọle ọrọ na li wa Anikanjọpọn ninu ọrọ yi o i sọ pe ọkan wa ni gbogbo wa. o yẹ ki a ma ya ẹya kan sọ tọ n si sọ pe ki gbogbo wa wa i irẹpọ, ki a sowọpọ fun ogo lẹ wa.

Imọran si Ijọba Apapọ Naijiria ni lati fun Ọlọla wa yi ni aye lati ye awọn ofin pelu lẹ wa wo, ki o le ṣe awọn atunṣe ti o tọ ati ti o yẹ, ki o si un ilẹ Naijiria ṣe.

Lakotan ọrọ mi yi, mo ki Ọlọla wa pe o ku ọrọ ilu. A jẹ gbo, A jẹ tọ ọjọ a dalẹ o

Emi ni.
Ajowa Akoko James Bamishele

## Ọdẹku Ekuṣeo

Nba dupẹ pupọ bi Olotu iwe irohin Imọlẹ ba le gba mi laye diẹ lati dupẹ lọwọ Ijọba Apapọ ti wọn gba ibo olori eto ọkọ ero (Bus) lọwọ awọn egbẹ alakukọ ti nwọn ti kuro ni alakoso Ijọba Ibilẹ Eko ti nwọn si gbe ipo na fun awọn egbẹ Afẹnifẹre ti nṣe akoso Ijọba Ibilẹ Eko nisisiyi.

Mo tun dupẹ lọwọ egbẹ Afẹnifẹre ti nwọn si ri pe ipo na to si ọgbẹni Julius Adeola Ọdẹku awọn egbẹ



Ọgbẹni Julius Ọdẹku

Afẹnifẹrẹ se ni ika ti o tọ sinu ni a fi remu ni nwọn fi gbe ipo na fun ọgbẹni J. A. Ọdẹku

Mo mọ pe ẹniti o le se iṣẹ na yọri gan ni nwọn gbe iṣẹ na fun odẹku Ọdẹku ti rin irin ajo kakiri orilẹ ede o si mọ iyọnu ti o wa fun awọn ti o nwọ ọkọ ero Bns na nri.

Lati se aniani asiko yi gan ni awa ti a ngbe ilu ati agbegbe rẹ yio gbadun Ọkọ ero na ni wiwọ ti ao mi mọ duro pa bi ere mọ, ti o run ati Ojo ko ni mo pa wa mọ nitoripe a fẹ wọkọ.

Ejẹ ki a sowọpọ ki a ran Ọgbẹni Ọdẹku lọwọ nitoripe ẹtẹ awọn ni ẹtẹ Ọgbẹni, ki a mọ da ẹru na da rara Ki a o sowọpọ fun ilọsiwaju ilu Eko

Teletẹle ẹgbẹ Afẹnifẹre ni o mọ eto na ṣe awọn ni ofi eto na lele

Eku iṣe Olotu
Emi ni
J. B Akanbi
Eko.


# EGBOGI JEDIJEDI

BERE EGBOGI



## "CYCLOVEN"

Aworan oke yi fi han gbangba ibiti Jedijedi rẹ gbe wa lara rẹ si nyọ ọ lẹnu nigbagbogbo. Ibẹ ni a npe ni "omusu" tabi Ibo idi enia ibiti a ma ngbe ṣe igbọnsẹ. Arun Jẹdijẹdi jẹ ọkan ninu amodi ti o buru ni pataki fun Ọkunrin ti o si lagbara pupọ lati ṣe iwosan rẹ patapata.

Ọpọlọpọ egbogi ni nwọn nta kakiri lode nisiyi ti wọn a ma po owo wọn fun iwosan rẹ ṣugbọn boya 1 a leri mẹwa ninu ọgọru ti o le ṣe iwosan arun yi daradara, Awọn ẹlomiran lero wipe bọya bi wọn ba lọ si ile Dokita lati lọ ke eyiti o ba nyọ jade lati omusu ku ni pa bẹ awọn o bọ lọwọ rẹ patapata.

Ṣugbọn awa ko ro bẹ rara. Lẹhin ọdun diẹ iyọnu rẹ yio si tun bẹrẹ bakana. Orisirisi Jedijẹdi ni o wa ekini ti o bẹrẹ nipa aiko mẹ ṣe igbọnsẹ dede tabi lojojumọ, ẹlomiran nipa ijoko ni ojukanna pẹlu lojoujmọ tabi gigun kẹkẹ ologere (Basikulu) pupọ ẹlomiran ewẹ nipa jijẹ Suga tabi oniruru ohun adidun pupoju nigbakugba. Jẹdijẹdi orisirisi ni o wa, ewo ni tirẹ? Bi o nyọ ade ninu omusu, tabi ti o ba nse ejẹ wa lehin igbọnsẹ, tabi ti o ba nyọ ti o ba ṣe igbọnṣẹ tan ni, tabi ti urin ọ ninu omusu ni eyikeyi ti o ba ra bere egboogi "CYCLOVEN" ti awọn Oyinbo Jamani ṣeṣẹ wa idi rẹ kio si panwo orisi meta ni o daju wipe iwọ yio bọ lọwọ Jẹdijedi patapata alafia yio de si ekeji rẹ ko si ninu gbogbo egbogi atata Lẹro Naijiria jakejado. Bere rẹ ni:

Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone: 22878 Nigeria, (Oja Ita Faji

ADEDUN CHEMIST
14' Wakeman Street, Yaba

ATI NI AWỌN ṢỌBU IBADAN:—
ṢẸ OLODUNMARE DISPENSARY OKE-BỌLA



## Iyipada Ile Isẹ

Eyi nilati kede fun awọn Onibara wa pe ati ko ile itaja wa kuro ni Ibadan patapata asi ti a si Ilu Itirẹ ni Agbe-be Suru Lere ati Mushin.

Enikẹni ti o ba fẹ bawa ra Iwe tabi Turari Ajẹbidan Erok wa si ile itaja wa ni Nọmba 11, Ishiba Street Odo



## Apejuwe le Isẹ Wa

E wọ Bọọsi ti o nlọsi Lawanson ni Yaba 3d pere ti oba sokale ni Lawanson, bere Ilu Itirẹ. Ti o ba de Ilu Itire bere ibiti nwọn ti npa malu, titi ibẹ ni itawe wa wa Ti o ba fẹ fi owo ranse fun ọja rẹ Adirẹsi mi niyi:-

Shoyinka
c/o Postal Agent,
Itirẹ Via,
Suru Lere, Yaba

AWỌN IWE TI O WA FUN TITA

| | |
|---|---|
| Iwe Egbogi Awo Igba Arun | |
| Iwe Egbogi Ajẹbidan | 20/- |
| Iwe Ala lati owo Josefu Alala | 25/- |
| Itumọ Ami Ara ati Etutu | 5/- |
| Iwe Ilana Yanrin tite ati Etutu Ṣiṣe | 20/- |
| Iwe Afọse Isẹdalẹ Yoruba ati psalmu Ajẹbidan | 4/- |
| Lilo ati Agbara psalmu | 7/- |
| Turari Isẹgun Ajẹ ati Adura Tete damilohun | 10/6d |
| Iwe Akọmọ Lesin Islam ati Orisirisi Iwe | 1/- |

# Ọlọrun Rinu

Lati ọwọ Hadji Awaiyewaṣere.

Ọpọlọpọ itan agbọkọgbọn ni awọn baba wa fẹran lati ma a sọ fun wa ni ọjọ ti inu wọn ba dun tabi ni ọjọ ti nwọn ba nfi igbadu se ayọ, ti nwọn si nyin Ọlọrun logo. Itan miran ninu awọn itan na yio kun fun aanu. Awọn omiran yio si pani lẹrin. Ṣugbọn onilaakaye ni ọrọ mbawi. Ẹni ti o ba ni laakaye ni o le gbọ itan na lagbọye ati lagbọkọgbọn. Ọlọrun, Olodumare, Ọba awọn ọba, Ọba Ogo, Ọba alaanu, a fi titobi ọla Rẹ bẹ Ẹ, fun awa ẹru Rẹ ni laakaye ati suru ti yio ṣe gbogbo wa ni anfaani o. Aamin.

Itan Ọlọrun rinu dun pupọ. Itan agbọkọgbọn ni o si jẹ. itan na si dun ju oyin lọ. Bi o si ti lọ si niyi, o:-

Ni akoko kan, ni igbalaila, awọn ọkunrin meji kan wa, ọkan dagba, o fẹrẹ to ẹni adọrin ọdun. Dogo ni o dudu minijọ. Ẹnu rẹ si dun pupọ, ẹlẹtan enia ni, arijẹ ninu idaru ni. A ma a fi ori ẹbi gba ara wọn. asi ma a fi ori aburo gba ori ẹgbọn, lati le ma a rijẹ ninu mọkaru. a ni ninu idaru, nigbati ọmọ ẹgbẹ rẹ kan ti irin-ajo ti o jinna de, ni ọjọ kan. o si bẹrẹsi ṣe apọnle rẹ, bẹ ifẹ oju ni poropo fẹ eera. O si pe awọn mọlẹbi wọn lai pe tabi lai jẹki ẹgbọn ọkunrin na ti o ti ajo de mọ nipa ipe na. O si k awọn jijọ ya fọto ayọ iranti ọjọ ti o ti ajo de pe ipe Ipe pajawiri ni o pe lọjọna.

Kawi, k'afoo, nwọn si ya fọto na bi nwọn si ti va tan, ni ẹgbọn Ọkunrin ti o ti ajo na de ri wọn. O si fura si wọn.

Fi ọgbọn ṣe iwadi lẹnu ọkan ninu wọn, o hun ti nwọn lọ ṣe. o si wa mọ pe, fọto ni nwọn lọ ya.

Lẹsẹkẹsẹ ni ẹgbọn na si ṣe ipe pajawiri, tirẹ fun yi ya fọto mọlẹbi awọn si yaa pẹlu aburo rẹ na ati awọn ẹbi wọn kanna. Ṣugbọn Ọkunrin arijẹ ninu idaru ko ba wọn ya fọto keji na. Nigbati onifọto na si ṣe eto orişirişi fọto mejeji na tan a eyi ti arijẹ ninu daru ya pọ pẹlu ẹni ti o tinrin ajo de ati awọn ẹbi, ko yori si rere. O ri jakujaku, ko ha n dada, ṣugbọn eyi ti o ya Ọlọrunrinu pọ mọ aburo rẹ ati awọn mọlẹbi si dara puro. Ṣe ẹ wa ghagbọ pe, Ọlọrunrinu, bi inu ba si ti ri ni obi ṣe nyan. Obi oninu buburu ki yan dada ẹ jẹ ki a ni inu ire inu oninububuru si bajẹ, o si sori kodo

Ẹ o ma ri pe, Ọlọrun rinu nitootọ Ẹ wa si ri pe, Ọlọrun ko si lẹhin alabosi, kii si gbe ẹbi fun alare

Mo be gbogbo ẹyin onkawe Aladun Irohin Imọlẹ, ẹfi itan yi kọgbọn, ki e si maa ṣe ẹtọ ni igbagbogbo. Ẹ maṣe kaṣa oninububuru o, Ọlọrun, a bẹẹ, ma a fi ọna han gbogbo wa o.


# MODUPE PRINTING PRESS

LEADERS IN MODERN PRINTING

*Many Firms Patronise MODUPE PRESS Because Of Their:—*

MODERATE CHARGES
EFFICIENCY
GOOD PRINTING
IMPERISHABLE RECORD
DELIGENT SERVICES
ACCELERATIVE METHODS OF PRINTING

*For Your Next Printing Jobs:—*

Just Call 21985 - Leave the rest to Modupe

We Guarantee Neat Work And Quick Service

**Modupẹ Printing Press**

**16, Bamgbose Street,**
Phone 21985, Lagos.


## YẸ IRAWỌ RẸ WO

**AQUARIUS** (Jan 22 - Feb 20) Ṣọra ki ẹjẹ ma yọ bi o ba ni ki o fi tipatipa yanju ọrọ kan to mbẹ nilẹ bi o ba le ṣe suru, boti wu ki ọrọ na le to, iwọ ni yio tori rẹ.

PISCES (Fe 21 - March 20) Alafia ara rẹ nfẹ amojuto. Maṣe fi ara silẹ fun aarẹ, o dara ki o ma daraya. Orire si mbẹ fun ọ lọnakọna

ARIES (Mar 21 - April 20) O fẹ, o kọ, o ni lati gba wipe ẹnikeji rẹ kanmọ iṣẹ ju ọ lọ, bi o ba wipe ki o jin lẹsẹ, o ntan ara rẹ jẹ lasan ni, o mọ iṣẹ ju ọ lọ

TAURUS (April 21 - May 20) Iwọ yio se afẹku owo ninu ọsẹ yi ṣọra nipa inawo to n a gbe owo ninu ọsẹ yi ṣọra nipa inawo to ma gbe owo rẹ lọ, ki o ma ba wa bẹrẹ si wipe amuwa Ọlọrun ni

GEMINI (May 21 - June 21) Tọju owo rẹ nipa ṣiṣọ owo na ki o ma si ṣe ohunti apa rẹ ko ka, ọrẹ rẹ kan ni yio yọ ọ kuro ninu gbese.

CANCER (June 22 - July 23) Iṣẹ yio pọ fun ọ ninu ọsẹ yi, ki o si ṣọrọ rẹ ki jamba kan maṣe ṣẹlẹ si ọ loni, maṣe mu ọbẹ tabi nkan ṣoṣoro dani loni, nitori ija to fẹ ṣẹlẹ maṣe sọrọ ti o le, sa fun ija

LEO (July 24 - Aug 22) Lọ ṣọra rẹ, ki o si mọ iru iwa ti iwọ yio ma hu si awọn aladugbo rẹ ati ọrẹ rẹ, ewu to wa nbẹ ko ni pẹ kuro.

VIRGO (Aug 23 Sept 23) Ẹkọ ati ọgbọn ori rẹ yio wale ninu ọsẹ yi Iṣẹ rẹ yio ma fa sẹhin ṣugbọn jẹki o tẹ ọ lọrun bẹ.

LIBRA (Sept 24 - Oct 23) Ṣọra ki o si ma kiyesi ọrọ ti o njade lẹnu rẹ idale ojiji le yọ si ọ laipẹ, ija kan si le bẹ silẹ lalẹ oni.

SCORPIO (Oct 24 - Nov 22) Oni ni ọjọ iṣẹ ti o ni lati lo ọpọlọ ori rẹ si, ọrọ ilu, tabi ọrọ ẹsin le gba ọ lọkan nipa bẹ nwọn le sọrọ ti yio fa ibinu wa fun ọ ẹsọ di ọwọ rẹ

SAGITTARIUS (Nov 23 - Dec 22) Fi ọgbọn sinu maṣe ba ẹnikeni jiyan ki o ba le jẹki irawọ rẹ ri aye tan imọlẹ si ọ lara. Wa ni irẹpọ pẹlu alabaṣe iṣẹ pẹ rẹ kan ti o nsọrọ rẹ ni ti daradara

CAPRICORN (Dec 23 - Jan 21) Maṣe gbe ti owo tabi ti dukia rẹ kan ti o sọnu ri ọkan, bi ọrọ rẹ ko tilẹ to lọd awọn obinrin. eyi ko buru ayipada titun miran lede


# PORAL

Bi amodi "IKỌ" ti ọjọ rẹ ti pẹ tabi ti o nyọ ọ lẹnn fun nkan bi ọdun kan tabi jubẹ lọ awọn egbogi rọbirobi ko le se iwosan rẹ rara, ma fi owo rẹ ṣe Ofo mo

Bere fun egbogi awọn ara, Ilu Faranse ti wọn npe ni PORAL ojulowo hanunhahun, atamatase egbogi fun. Ikọ here, Ikọ otutu, Ikọ ọna ọfun, Ikọ igbaaya, Ikọ lile. Ikọ, ti o ma mu enia tu kẹlẹbẹ nigbakugba lati inu "Ifun wa (Lungs) tabi ti o ba nmu enia ru pẹlu.

Bi o ba dan Igo kan PORAL yi wo Iwọ na yio ri iyatọ ninu ara rẹ ni kiakia Igbaaiya tabi ọna ọfun rẹ ti o ma nho yio duro "IKỌ" rẹ yio si san ni patapata iwọ y'o ma jẹun daradara iwọ yio si sun fọnfọn pẹlu alafia de

Bere egbogi yi ni awọn orişirişi Egbogi Ikọ miran ni Ṣọbu awọn:-

Waterloo Medicine Stores
Phone:- 2278 (Ọj, Lagos Nigeria
8, Palmchurch Street, Ita Faji)

# Asọbade Orire Ere Bọọlu

| | | | |
|---|---|---|---|
| NEW SOUTH WALES | | | |
| Mayfield | v | Wajlse:d | x |
| Bankstown | v | Apia | 1 |
| Canterbry | v | Corinthians | 1 |
| Thistle | v | Sydney A. | 1 |
| Western | v | Manly | 1 |
| QUEENSLAND | | | |
| Redbank | v | Merton | 2 |
| Germania | v | Easts | x |
| Hollandia | v | Dinpro | 1 |
| St. Helens | v | Taringa | x |
| VICTORIA STATE | | | |
| Alexander | v | Juventus | 2 |
| Lion | v | Hakoah | x |
| Polnia | v | Triestina | 1 |
| Slavia | v | JUST | 1 |
| S. Mel'rne | v | Wilhelmina | 1 |
| VICTORIA-DIV. 1 | | | |
| Austria | v | Oakleigh | 1 |
| Box Hill | v | Bayswater | 1 |
| Coburg | v | richmond | 1 |
| Croatia | v | Dandenon | 1 |
| Moreland | v | Mekedonia | 2 |
| Snushine C. | v | Sand'ham | 2 |
| VICTORIA-DIV 11 | | | |
| Ferntree | v | Collingwood | x |
| Libertas | v | Moonee | x |
| Panran | v | S. Yarra | 11 |
| St. Albans | v | Brighon | 1 |
| University | v | Flinders | x |
| Williamstown | v | p. Ranecs | |
| VICTORIA-DIV 111 | | | 2 |
| LCL | v | Frankston | 1 |
| Moorabiu | v | Croydon | |
| Northcote | v | Heidelberg | |
| Ringwood | v | Sunhin | H |
| Springvale | v | Essendo | 11 |
| VICTORIA-Div. IV | | | |
| Albion | v | Ajax | x |
| Chelsea | v | Mooroolbark | 1 |
| Hercules | v | Waverley | 1 |
| Huntingdale | v | Flemington | 1 |

| | |
|---|---|
| Melita v Glenroy | 2 |
| Tullamrine V Helvtic | 1 |
| S. AUSTAL IA- DIV | 2 |
| Birkalla v Polonia | x |
| Cumberland v Budapest | 1 |
| Eufield v Bubapest | 2 |
| Hellas v Austria | |
| Juventus v Victoria | 1 |
| S AUSTALIA-DIV, | 11 |
| Elizabeth v Napoli | 1 |
| Lion v Beograd | 1 |
| Pt. Adelaide v Ediburgh | 2 |
| Saisbury v Malta | x |
| Wr v Orange | 1 |
| W AU ALIA CUP | 1 |
| Athena v Olympic | |
| Crhcovi v Azzurri | |
| Emau v M. Juvehtus | x |
| Ilia v Kiev | 1 |
| Muscecabean v Peith | x |
| Macadaionia v Bayswater | 1 |
| N. Perth v Windmills | 1 |
| Queens pk v Medina | 1 |
| S. Perth v Caledonia | x |
| Sporth v Brittania | 2 |
| Swan Ath v Swan Valley | 2 |
| Tricolore v Spearwood | x |
| University v Subiaco | 1 |

## Selections

My homes selections are: Polonia (V) Box Hill Croatia (V) Ringwood Juventus (SA), Elizabeth, Lion (SA), N. Perth, Tricolore, Enfield, Prahram, Coburg and Slavia.

## Abayọri Orire Ere Bọlu Ọsẹ To Kọja

| | | | | |
|---|---|---|---|---|
| NSW NORTH DIVISION I | | | | |
| Adamstown | 3 | Newcastle | 2 | |
| NSW FEDRATION DIVISION | | | 1 | |
| Hellenic v South Coast (Post-Poned) | | | | |
| Budapest | 1 | Bankstown | 1 | |
| Croatia | 2 | Prague | 1 | |
| NSW FEDRATION DIVISION | | | 11 | |
| Melita | 2 | Thistle | 1 | |
| Sydney | 3 | Sutherland | 3 | |
| VICTORIA DOCKERTY CUP ROUND | | | 11 | |
| Bayswater | 2 | Moonee | P. | |
| Dandenong | 2 | Sandringnam | | |
| (After extra time) | | | | |
| Makedonia | 4 | Flinders | 3 | |
| Springvale | 2 | Park Ranges | 0 | |
| Essendon | 1 | Melita | 4 | |
| Prahran | 0 | Sunshine C. | 1 | |
| Moreland | 3 | Richmond | | |

| | | | |
|---|---|---|---|
| (After xtra time score at ninety minutes one-one) | | | 0 |
| St, Albans | 4 | ICI | 3 |
| Coburg | 4 | Austria | 3 |
| Ferntrree | 2 | Croatia | 1 |
| Heidelberg | 3 | Moorabbin | 1 |
| Chelsea | 2 | Glenroy | 1 |
| Frankston | 0 | Collingwood | 3 |
| Northcote | 5 | Alax | 6 |
| (After extra time score at ninety minutes five-five) | | | |
| University | 3 | Hercules | 1 |
| (Abandoned after 66 minutes Match awarded University) | | | |
| Boxhill | 1 | Albion R | 0 |
| (After extra time score at ninety minutes zero-zero | | | |

QUEENSLAND STATE LEAUE

| | | | |
|---|---|---|---|
| Merton | 3 | Oxley | 2 |
| Thistle | 4 | Coalstars | 1 |

## Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

Ipade gbogbo gbo o yio wa fun awọn ọmọ ẹgbẹ Imọlẹ Ayie ni ọjọ keje oṣu kẹfa (7/6/64) ni deede agogo meji ọsan ni nọmba 16, Bamgbose Street Eko.

Ao si tun fi tayọtayọ gba awọn ọmọ ẹgbẹ titun ti nwọn ba wa si ipade lati jẹ ọmọ ẹgbẹ.

Ki ẹ tete de o

LATEEF BABALOLA
Akọwe Agba


BI O BA NI
# Iwe—Titẹ
FUN
**Lilo nibi Iṣẹ rẹ tabi orişirişi iwe itufọ tabi ijade Oku**
ATI
**Iwe Igbeyawo**
TETE KỌWESI ILE–IṢẸ–ẸRỌ ITẸWE
**Modupẹ Printing Press**
16, Bamgboṣe Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985, Lagos.
KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN
*OWO PỌKU NI A SI NGBA*
IROHIN KO TO AFOJUBA
*Dan wa wo lẹẹkanṣoṣo ki o ri iyatọ*



GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ati AYỌ NIPA "DYNAMIREN" TỌNIKI

ALE-BI-ELE Egbogi Tọniki awọn Jamọnu titun ti gbogbo ara Ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ daju fun Akọ agbara ati Ajẹbidan işẹ Rẹ lara Agbalagba Ọkunrin gbogbo



Bi arẹ ara ba nmu ọ, nigbakugba fun wahala tabi işẹ şişe ti o ko le jẹun daradara, tabi ki o male sun daadaa okun lọsan tabi loru tabi awọn işan ara rẹ gbogbo ki şe fun daradara ti Eemi (Breath) inu ko ba gunlẹ daradara wọn işẹ tabi wahala şişe tabi fun awọn alera gbogbo ‘nyin ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti kọja Ọgbọn ọdun o si de adọrin tabi jubẹ lọ. Mo dupẹ "DYNAMIREN ni egbogi ti e nfẹ lati sọ ara di ọtun patapata, oju rẹ a si jọlọ, ẹran ara rẹ ti o ti hunjọ yio bẹrẹ s'i dan pada. Ara rẹ yio ma gbe kankan nigbakugba d'Arẹ" nigbakugba yio salọ pelu. Igba-dun ati alafia yio de si ọ. Iyẹn daju. Bere Egbogi na ni Şọbuza

Waterool Medicine Store
8, Palm Church Street, Lagos

PILENAB MIXTURE',
Egbogi olomi dara julọ fun awọn ọmọde ti jẹdijẹdi bi aiko gbọrşẹ dede ba nyọ lenu bere rọ ni
WATERLCO MEDICINE STREES
'AFAGBEWESA STREET, OSHOGBO.

# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ AIYE, ORE T'ENI GBOGBO LAWA

No. 706 FRIDAY MAY 29 1964 (2D)


## Felix Ha Gba Owo Lọwọ Adisa Bi ?

IBADAN:— Gbogbo ile lo palọlọ ti ẹṣẹ ko si gbeji nigbati awọn Ọlọpa mu Ọdaran Ọlọpa kan, Felix Harbor, ẹni ọdun mẹtalelogun wa siwaju adajọ fun ẹsun owo ẹhin ati riba ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹdọgbọn oṣu yi.

Ọlọpa ti o ba Ọdaran Ọlọpa na ṣẹjọ ṣe alaye pe, ni ọjọ kẹtalu oṣu kẹ'a ọdun yi ni Ọdaran Ọlọpa na ri ewe taba igbo lọwọ Adigun Adelabu nigbati o si nmu ni ọrẹ Adelabu, Rafiu Adisa ba fun Felix ni ponun marun, (£5) pe ki o ma ṣe ba Adelabu ṣẹjọ.

Ọlọpa na tun ṣe alaye siwaju pe Ọdaran Ọlọpa na lo kọkọ bere pe, bi nwọn ba fẹ ki on fi wọn silẹ, ki nwọn da omi siwaju.

Lẹhinti Ọlọpa na sọ bayi tan, ni awọn enia na ba lọ fi ọro na han Ọlọpa ni Teṣan, Ọlọpanu kan si ko owo na fun wọn, eyiti ati ṣami si lara, bi nwọn ti ko owo na fun un, ti o si fẹ ma a lọ ni Ọlọpanu ba ragabu rẹ, o si ba owo na ninu apo rẹ.

Adajọ ti yẹ gbiggọ ẹjọ na si ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kẹrindinlọgbọn oṣu ti mbọ lori iduro ọgọrun pọnun (£100) ati onigbọwọ iyekenna. Bi nwọn ba ti pari ẹjọ na si, ẹo tun ma a gbọ ninu Iwe Irohin wa.

# Awọn Oṣiṣẹ Fẹ Da Iṣẹ Silẹ

## Lati Oju Ewe Kini



Alhaji Abubakar Balewa

fun obunkohun ti awọn oṣiṣẹ ba ṣe, nitori, e o ni iwọn iba ti ọmọ enia le mu suuru mọ."

Ọgbẹni Wahabi Goodluck, ọkan nina awọn alaga Igbimọ ẹgbẹ awọn oṣiṣẹ fi ilodisi ọkan rẹ han awọn oṣiṣẹ lori ẹkunwo oṣu ti nwọn ṣe na.

O ni awọn ti Igbimọ oluwadi na sọ pe ki nwọn ma a gba pọnun mejila (£12) o ni pọnun mẹrindinlogun ṣile mẹrindinlogun (£16: 16/-) lo yẹ ki awọn enia na o ma a gba lo'ṣu.

O ni awọn Oṣiṣẹ ti Igbimọ Morgan sọ ye ki nwọn o ma a gba pọnun mẹwa (£10) o ni pọnun mẹdogun ṣile mẹsan ati nain (£15 : 9s 9d) lo yẹ ki nwọn o ma a gba.

O ni awọn Oṣiṣẹ ti Morgan sọ pe ki nwọn o ma a gba pọnun mẹjọ, (£8 o ni pọnun mẹtala ṣile meji (£13 : 2/-) lo yẹ ki awọn Oṣiṣẹ na ma a gba.

Ọgbẹni Good-luck wa pari Ọrọ rẹ pe, awọn Oṣiṣẹ ti Igbimọ Morgan sọ pe, ki nwọn o ma a gba, pọnun mẹfa abọ (£6 : 10/-) o ni pọnu mọkanla lọ yẹ fun wọn lati ma a gba ni Oṣoṣu.

Ninu ọrọ ti rẹ, ọgbẹni M. A. O, Imoudu, sọ pẹlu iyanu pe, ko ni jẹ ohun ti o dara lati rii wipe Ijọba ti o wa lode nisisiyi na ni yio si tun maa ṣe Ijọba lọ titi.

Ọgbẹni Imodu tun sọ pe "Awọn oṣiṣẹ jakejado orilẹede yi ko ni igbakẹlẹ nina Alhaji Abubakar Tafawa Balewa, Alakoso Apapọ Ijọba Naijiria ati Ijọba rẹ."

O tun sọ siwaju pe iwadi Igbimọ Morgan ko wa isọkan orilẹ ede yi nitoripe o pin gbogbo rẹ si wẹwẹ ko si pa gbogbo rẹ si ọna kanṣoṣo.

Nipa Ofin ti Ijọba ṣe pe ko gbọdọ si ipade Ode gbangba tabi iwode, Ọgbẹni Imoudu sọ pe "Gbogbo wa li ao to yika ni Ọjọ na, ao si ba Ofin na jẹ."

Ki ipade na to pari, gbogbo awọn Oṣiṣẹ na ni nwọn pa ẹnu pọ si Ọnakanṣoṣo pe, awọn yio ṣe ipade kan ni Ọjọ Abamẹta ti iṣe Ọgbọnjọ Oṣu yi, ti iwe Ijọba na ko ba fi jade,

Ninu ile Ọti (Hotel Majestic) ni nwọn o ti ṣe ipade na ni irọlẹ Ọla lati mọ gbogbo eto ti nwọn o ba ṣe fun imurasilẹ fun idaṣẹ silẹ na ni Ọjọ mẹrin oni

Onirohin wa kan fi ye pe Ninu awọn nkan ti nwọn o gbe lọwọ ni ọjọ na nwọn ti ṣe eto silẹ. Awọn kan lọ kọ awọn ọrọ kan si ara pali eyiti awọn oṣiṣẹ na yio gbe lọwọ ni ọjọ na.

Ninu awọn pali diẹ ti oniwe irohin wa ri, awọn ohunti nwọn kọ si wọn lara ni wọnyi "A ko fẹ Irohin wadi owo-oṣu Morgan, A fẹ gbọ Ipinnu Ijọba lori iwadi ẹkunwo oṣu na. A ko tilẹ fẹ Ijọba yi mọ."

Nigbati nwọn pari ipade na tan, ni awọn oṣiṣẹ ba lọ gbe Ọgbẹni Imoudu ni kọkọ lorun kakiri gbogbo adugbo ti nwọn ṣe ipade na

Onirohin wa ran wa leti pe, ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kẹtadinlọgbọn oṣu yi ni Apapọ Ijọba gbe Irohin abayọri iwadi ẹkunwo oṣu awọn Oṣiṣẹ eyiti Igbimọ Morgan ṣe.

Ninu abayọri irohin ẹkunwo oṣu na, Igbimọ na sọ pe, ẹniti o ba ngba pọnun Ọrindinrinwo pọnun (£318) ni ọdun kan, ki Ijọba fi pọnun mẹrindinlogoji (£36) kun owo wọn. Eyi ni pe, ẹni ngba pọnun mẹrindinlọgbọn (£26) ki Ijọba ma a san pọun mọkandinlọgbọn (£29) fun wọn ni Oṣoṣu.

Awọn ti nwọn ba ngba pọnun mẹrindinlogoji (£36 ni oṣoṣu ki ijọba fi pọuun meji (£2) kun owo wọn ki nwọn si ma a gba (£38) loṣoṣu.

Awọn ti nwọn ba ngba pọnun mọkandinl a d ọ t a (£49) ki Ijọba fi pọnun kan kun owo wọn loṣu ki nwọn si ma a gba adọta (£50) loṣoṣu

Igbimọ na sọ pe, gbogbo awọn oṣiṣẹ ti owo oṣu wọn ba ti kọja adọta (£50) ni oṣu kan ki Ijọba maṣe fi owo kun owo oṣu wọn, nitoripe owo ti nwọn ngba loṣu to wọn ra di ipari oṣu.

Igbimọ na paṣẹ pe. ki Ijọba o lọ san owo ọya fun awọn oṣiṣẹ lati oṣu kẹwa ọdun ti o kọja yi, eyi si jẹ oṣu mẹjọ ti awọn oṣiṣẹ yio gba owo rẹ, ṣugbọn awọn ti owo oṣu wọn ba kọja adọta pọnun ni oṣu kan ko ni gba ninu owo ọya na.

Bakanna ni Igbimọ na tun pa laṣẹ pe," ki Ijọba ma a fi pọnun mejila (£12) bẹrẹ fun awọn lebira ni Eko ati agbegbe rẹ.

Igbimọ na tun paṣẹ pe ki Ijọba maṣe san owo ojumọ mọ fun awọn oṣiṣẹ, ṣugbọn ki nwọn ma a san owo oṣu fun gbogbo awọn oṣiṣẹ.

Ṣugbọn ninu gbogbo imọran ti Igbimọ Morgan la si'ẹ fun Ijọba, Ijọba ko ti sọ bi awọn faramọ imọran na tabi awọn ko ni faramọ Lori aiko sọrọ Ijọba yi ti awọn oṣiṣẹ ko si ti mọ ohun ti Ijọba le ṣe ni nwọn ṣe pinnu lati da iṣẹ silẹ.

Onirohin wa kan sọ pe ninu ipade ti awọn o se ni ọla ni nwọn o ti pinnu ti nwọn o si tun sọ ohun ti nwọn o se ni ọjọ mẹrin ti nwọn fẹ dẹ iṣẹ silẹ.

Ṣugbọn Ijọba ti ṣe Ofin pe ko gbogbo si iwode tabi ipade Ode gbangba. A gbọ wipe Ofin yi le mọ jẹki awọn Oṣiṣẹ na o le ṣe iwọde gẹgẹbi nwọn ti ṣe pinnu.

Oniwe irohin wa yio lọ si ibi ipade na, gbogbo Ohunti nwọn ba si sọ ninu pade na. ẹo ma a gbọ

## E ma a Ka Iwe Irohin Imọlẹ Lojojumọ


## CLASSIFIED ADVT.

"KIU FUNG MANUFACTORY BOX 3812 HONGKONG, IMITATION JEWELLERY WIRE HOOKS".



Printed and Published by Modupe Printing Press 16, Pangbose Street Lagos Phone 21985
Editor:- TUNJI ADEOSUN 45, Campbell Street, Lagos 29/5/64